# AWỌN ẸKỌ JESU NIPA JÍJẸ́ ỌMỌ-ẸYIN

## Matteu 17:14-21; Luku 9:51-62

## ẸKỌ 115 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ko si ẹni, ti o fi ọwọ́ rẹ̀ le ohunelo itulẹ, ti o si wò ẹhin, ti o yẹ fun ijọba Ọlọrun" (Luku 9:62).**

### Adura Baba Kan

Jesu pẹlu Peteru Jakọbu ati Johannu, sọkalẹ lati ori oke nibi ti a ti pa A lara dà. Awọn ọmọ-ẹyin iyoku ati ọpọlọpọ eniyan pade wọn, laaarin wọn ni ẹni kan ti o mọ ewo ninu wọn ni i ṣe Oluwa ti jade wá. Ọkunrin naa, ẹni ti o n wá aanu, kunlẹ niwaju Rẹ̀. O tọ Jesu lọ nitori ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo (Luku 9:38). Ẹmi eṣu ni o n dá ọmọ naa loro, o ti wà ninu irora buburu to bẹẹ ti o ṣe e ṣe ki o má le gbadura fun ara rẹ̀. A n dá a loro ninu ọkàn rẹ̀, a si maa ṣubu sinu iná nigba miiran ati sinu omi nigba miiran.

Awọn ọmọde miiran kò mọ riri nini awọn obi ti n gbadura. Ko si ẹni ti o mọ ohun ti i ba ṣẹlẹ si ọmọdekunrin yii bi baba rẹ ko ba bikita fun un, ki o mu un wá sọdọ Jesu, ki O si gbadura fun un nigba ti oun tikara rẹ̀ ko le gbadura fun ara rẹ. Awọn eniyan wà ni akoko yii ti wọn ni iru ẹri ti ọkunrin yii le sọ; awọn obi wọn mu wọn tọ Jesu lọ sinu adura, Ọlọrun si dá ide ẹṣẹ O si gbà wọn. Bi o ba ni obi ẹni iwa-bi-Ọlọrun o yẹ ki o mọ̀ pe ẹni ibukun Ọlọrun ni iwọ i ṣe. O yẹ ki o kun fun ọpẹ́ nitori wọn.

### Orisun ti O Tọ́

Ẹni ti o tọ́ gan an ni baba ọmọdekunrin naa mu un tọ lọ nigba ti o mu un wá sọdọ Jesu. Aṣẹ fun awọn alaisan lọjọ oni ni lati lọ sọdọ Jesu. Bi ẹni kan ba ṣaisan o le ri iwosan nipa wiwa sọdọ awọn alufaa ki wọn gbadura fun un, ki wọn si fi ororo kun un ni orukọ Oluwa (Jakọbu 5:14, 15).

Inu ọkunrin naa bajẹ nitori awọn ọmọ ẹyin ko le wo ọmọde naa sàn (Luku 9:40); boya eyi si mu ki igbagbọ rẹ̀ mì pẹlu. Pẹlu itara ẹni ti o n fẹ iranlọwọ lọnakọna o bẹbẹ, "Bi iwọ ba le ṣe ohunkohun, ṣãnu fun wa, ki o si ràn wa lọwọ" (Marku 9:22). Igbagbọ rẹ̀ fẹrẹ lọ tán, ṣugbọn Jesu mu un lọkan le pe nipasẹ igbagbọ ni a fi maa n ri ibukun gbà. "Bi iwọ ba le gbagbọ́, ohun gbogbo ni ṣiṣe fun ẹniti o ba gbagbọ́" (Marku 9:23). Ọkunrin yii wa mọ ohun ti o n ṣe idena – aini igbagbọ́. Pẹlu omije o bẹ̀bẹ̀ pe ki Oluwa ki o ran aigbagbọ oun lọwọ (Marku 9:24). Bi Jesu ti bá ẹmi aimọ naa wí, ara ọmọ naa si dá -- ki i ṣe diẹdiẹ ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ.

### Agbara lori Eṣu

Jesu ti fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ ni agbara lati lé awọn ẹmi eṣu jade ati lati ṣe iwosan gbogbo arun ati gbogbo aisan (Matteu 10:1), ki ni ṣe nigba naa ti wọn ko le wo ọmọ naa sàn? Jesu ba wọn wi nitori aigbagbọ wọn. O bẹrẹ si i woye bi yoo ti pẹ to ki awọn ọmọ ẹyin to mọ̀ pe agbara naa ki i ṣe ti awọn tikara wọn bi ko ṣe ti Oluwa. Ọlọrun ti fi agbara fun Jesu lati ṣe rere ati lati wo gbogbo awọn ti eṣu n dá loro sàn, nitori Ọlọrun wà pẹlu Rẹ̀ (Iṣe Awọn Aposteli 10:38).

Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ pe o gba adura ati igbagbọ lati ni agbara Ọlọrun. O sọ pe ko si ohun ti yoo ṣoro bi wọn ba ni igbagbọ́ bi horo irugbin mustardi, eyi ti o jẹ́ kekere, ṣugbọn ti o ni anfaani pupọ lati dagba ki o si di igi nla nigba ti o ba ri awọn nnkan ko-ṣe e má-ni lati mu un dagba. Bẹẹ ni o ri pẹlu igbagbọ: bi o ba tilẹ jẹ kekere sibẹ o le dagba, ki o si maa pọ̀ si i. "Njẹ nipa gbigbọ ni igbagbọ́ ti iwá, ati gbigbọ nipa ọ̀rọ Ọlọrun" (Romu 10:17).

Jesu n fẹ ki awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ ni igbagbọ́ ati agbara lati Oke wá. A ti pè wọ́n lati tan Ihinrere kalẹ, nipa agbara Rẹ̀ ni awọn eniyan yoo fi mọ̀ pe ọmọ ẹyin Rẹ̀ ni wọn i ṣe. "Àmi wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn o ma lé awọn ẹmi èṣu jade. . . . . . nwọn o gbé ọwọ́ le awọn olokunrun, ara wọn ó da" (Marku 16:17, 18). Jesu sọ fun wọn bi wọn ṣe le ri agbara yii gbà – nipa adura ati aawẹ.

O hàn gbangba pe awọn ọmọ ẹyin jere nipa awọn itọni Jesu; nitori a kà pe nigba ti Jesu rán awọn aadọrin ọmọ ẹyin lati waasu, wọn pada pẹlu ayọ̀, wọn si wi pe, "Oluwa, awọn ẹmi èṣu tilẹ foribalẹ fun wa li orukọ rẹ" (Luku 10:17).

### Lati Wá ati Lati Gbala

Jesu n mura awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ silẹ de ọjọ ti a o gba A kuro lọdọ wọn, ti iṣẹ itankalẹ Ihinrere yoo si di ti wọn. Bi ọjọ naa ti n sunmọle wọn mu ọna wọn pòn lati lọ si Jerusalẹmu. A ko gba wọn ni ileto awọn ara Samaria kan, awọn eniyan naa ko si fẹ gbọ́ ọrọ Jesu. Jakọbu ati Johannu ro pe ko yẹ ki wọn ṣe bẹẹ si Oluwa, lẹṣẹkẹṣẹ ni wọn si beere aṣẹ lati pa awọn eniyan naa run.

O wa ni ipá Oluwa lati pe iná sọkalẹ lati Ọrun lati jẹ awọn eniyan naa ni iyà bi O ba ri pe o tọ́ lati ṣe bẹẹ. Ni idahun si adura Elijah, Ọlọrun rán iná sọkalẹ lati sun ẹbọ naa ati lati fi han awọn oluwa Baali pe Oun nikan ṣoṣo ni Ọlọrun (1 Awọn Ọba 18:38, 39).

Jesu kò fi aṣẹ si i pe ki a pa awọn ara ileto Samaria yii run, nitori O sọ pe eyi lodi si ẹmi Onigbagbọ́. "Ẹ máṣe fi buburu san buburu fun ẹnikẹni" (Romu 12:17). "Oluwa wipe, Temi li ẹsan; emi ó gbẹsan" (Romu 12:19). Lẹyin eyi, wiwa Jesu ki i ṣe lati pa ẹlẹṣẹ run ṣugbọn lati fun un ni anfaani lati ronupiwada ki o si ni iye ainipẹkun. "Nitori Ọmọ-enia de lati wá awọn ti o nù kiri ati lati gbà wọn là" (Luku 19:10).

**Awọn Ohun Amuyẹ**

Jesu n kọ́ wọn gẹgẹ bi o ti yẹ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ lati maa gbé igbesi-aye wọn, ati ohun ti yoo gbà wọn lati jẹ́ ọmọ ẹyin Rẹ̀. Awọn miiran wà ti wọn kò le ṣe ọmọ ẹyin nitori wọn ko le fi ara wọn si ipò ti o yẹ. Ọkunrin kan fi iwarapàpà sọ pe oun yoo tẹle Jesu nibikibi ti O ba n lọ. Jesu mọ pe kò ti ṣiro ohun ti yoo gba a. "Nitori tani ninu nyin ti npete a ti kọ́ ile-iṣọ, ti ki yio kọ́ joko ki o ṣiro iye owo rẹ̀, bi on ni to ti yio fi pari rẹ̀. Ki o ma ba jẹ pe nigba ti o ba fi ipilẹ ile sọlẹ tan, ti kò le pari rẹ̀ mọ́, gbogbo awọn ti o ri i a bẹ̀rẹ si ifi i ṣe ẹlẹyà" (Luku 14:28, 29). Jesu mọ pe ọkunrin yii dabi ẹni ti Oun tọka si ninu owe afurugbin ati irugbin ti o bọ́ si ilẹ apata (Matteu 13:5, 6, 20, 21) ẹni ti o fi ayọ̀ gbà lati maa tẹle Jesu titi inunibini ati ipọnju fi de lati dán igbagbọ́ rẹ̀ wò. Ko ni gbongbo; iriri rẹ jẹ eyi ti ko jinlẹ, yoo si lọ kuro lai pẹ. Jesu ko sọ fun un pe ki o má ṣe tẹle Oun, ṣugbọn Jesu sọ fun un pe ọna naa ki yoo jẹ eyi ti o rọrun. Jesu ko ṣeleri ọna ti o rọrun. ṣugbọn O ṣeleri lati ṣe iranlọwọ: "Ore-ọfẹ mi to fun ọ" (2 Kọrinti 12:9). "Kò si idanwò kan ti o ti ibá nyin, bikoṣe irú eyiti o mọ̀ niwọn fun enia: ṣugbọn olododo ni Ọlọrun; ẹniti kì yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn ti yio si ṣe ọna atiyọ pẹlu ninu idanwò na, ki ẹnyin ki o ba le gbà a" (1 Kọrinti 10:13). Ọkunrin naa ni lati yàn, ṣugbọn a kò gbọ́ pe o tẹle Oluwa.

**"Ọlọrun ko ṣeleri awọsanma daradara,**
**Ipa-ọna ti o kún fun itanna ni gbogbo ọjọ ayé wa.**
**Ọlọrun ko ṣeleri oorun laisi òjò,**
**Ayọ̀ laisi ibanujẹ, alaafia laisi irora.**
**Ṣugbọn Ọlọrun ṣeleri agbara fun ọjọ kọọkan**
**Isinmi fun oṣiṣẹ, imọlẹ ninu ọna,**
**Oore-ọfẹ fun idanwo, iranlọwọ lati oke wá,**
**Ibakẹdun ti ki ikuna, ifẹ ti kò le kú."**

Jesu pe ọkunrin miiran lati ṣe ọmọ ẹyin Rẹ̀, ṣugbọn ọkunrin naa ṣe awawi (Luku 9:59, 60). (Ka Luku 14:16-24). O n fẹ lati sún ọjọ́ naa siwaju di igba miiran. O ni oun ni ojuṣe kan lati ṣe fun baba oun. Kò ronu nipa ojuṣe ti ẹmi ti o ni lati ṣe fun Baba rẹ̀ ti n bẹ ni Ọrun. Jesu sọ fun un pe ọpọlọpọ eniyan ni wọn ṣi wà - ti wọn jẹ́ okú ninu ẹ̀ṣẹ ti wọn kò ni anfaani irú ipè giga bayii – ti wọn le bojuto eto isinku baba rẹ̀ nigba ti o ba kú. Ṣugbọn ọkunrin yii ti fi aniyan ohun ti ayé yii kún ọkàn rẹ̀ pupọ jù, o si jẹ idiwọ fun un, o hàn gbangba pe kò gbọran si aṣẹ Jesu wi pe, "Iwọ lọ ki o si mã wãsu ijọba Ọlọrun." "Ṣugbọn ẹ mã kiyesara nyin, ki ọkàn nyin ki o máṣe kún fun wọ̀bia, ati fun ọti amupara, ati fun aniyan aiye yi, ti ọjọ naa yio si fi de ba nyin lojijì bi ikẹkun" (Luku 21:34).

Ẹlomiran ni oun yoo tẹle Jesu, ṢUGBỌN awọn nnkan kan wà ti o kọ́kọ́ fẹ́ lati ṣe ná; nitori naa o kọminú. O fẹ lati lọ dagbere fun awọn eniyan rẹ̀ bi ẹni pe inira ni o jẹ fun un lati fi wọn silẹ. Eyi yii yatọ si ẹmi ti Eliṣa, ẹni to pa gbogbo nnkan wọnni run ti i ba fa a sẹyin lati má tẹle Oluwa (1 Awọn Ọba 19:21). "Eliṣa jó gbogbo afara ti o wà lẹyin rẹ̀."

**Kò Yẹ fun Ijọba Naa**

Jesu tọka si ewu ti o wà ninu bibojuwo ẹyin wo ohun ayé yii. Oun ko wi pe "yiyipada" ṣugbọn "bibojuwo ẹyin" yoo mu ki eniyan ṣe alaiyẹ fun Ijọba Ọlọrun. Bibojuwo ẹyin ni pe eniyan ko fi gbogbo ọkàn rẹ̀ tẹle Jesu, ṣugbọn o ni oungbẹ ninu ọkàn rẹ̀ fun awọn nnkan igbesi-ayé atijọ. Ninu Gẹnẹsisi 19:26, a kà nipa ohun ti o ṣẹlẹ si iyawo Lọti nigba ti o bojuwo ẹyin. Nitori iwa buburu, Ọlọrun pa ilu Sodomu run, nibiti Loti ati ẹbi rẹ̀ n gbé. Ni idahun si adura arakunrin baba Lọti, Abrahamu, Ọlọrun kilọ fun Lọti lati sá asala fun ẹmi rẹ̀ lai bojuwo ẹyin. A sọ fun wa pe ki a "ranti aya Lọti" (Luku 17:32) nitori o bojuwo ẹyin o si di ọwọ̀n iyọ̀ -- apẹẹrẹ aigbọran. Ki Oluwa jẹ ki eyi jẹ ikilọ fun bibojuwo ẹyin ati fun ṣiṣe aigbọran.

Ọlọrun ko fẹ ki awọn eniyan Rẹ sin In pẹlu ọkàn ti o pín yẹlẹyẹlẹ. "Nitori emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, Ọlọrun owú ni mi" (Ẹksodu 20:5). Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ" (Deuteronomi 6:5). Ni ọna bayii kò ni si àye fun nnkan miiran ninu ọkàn.

Jesu ti fi apẹẹrẹ giga lelẹ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀, ọpọlọpọ ni o si ni ero lati gbaradi lati de odiwọn yii ki wọn si gbé e ró. Paulu Apọsteli wi pe: "Ẹ jẹ ki a pa ohun idiwọ gbogbo tì si apakan. . . . . . ki a si mã fi sũru sure ije ti a gbé

ka iwaju wa, ki a mã wò Jesu olupilẹṣẹ ati alaṣepe igbagbọ́ wa" (Heberu 12:1, 2). "Ohun kan yi li emi nṣe, emi ngbagbé awọn nkan ti o wà lẹhin, mo si nnọgà wò awọn nkan ti o wà niwaju, emi nlepa lati de opin ire-ije nì fun ère ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:13, 14).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti awọn ọmọ ẹyin kò wo ọmọdekunrin naa sàn?
2. Bawo ni eniyan ṣe le ri agbara Ọlọrun gbà sinu ayé rẹ̀?
3. Ki ni ṣe ti Jesu fi wá sinu ayé yii?
4. Ki ni itumọ gbolohun yii: "jó awọn afara ti o wà lẹyin rẹ̀?"
5. Njẹ Ọlọrun beere gbogbo ọkàn rẹ?
6. Darukọ ohun mẹta ninu ẹkọ yii ti Jesu n beere lọwọ awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀.